# TANI ALAKOSO OKAN RE



TANI O WU O KI O MA GBE INU OKAN RE?

## OLORUN NI TABI SATANI

IDAHUN RE NI YOO FI IBI TI IWO
**YOO WA TITI LAYELAYE HAN**

# NJE IWO TI NI IFE PUPO SI ENIKAN RI?

## BOYA SI OBIRIN, OKUNRIN, IYA, BABA TABI ORE KAN?

A je wipe o le mo ninu okan re bi ife ti o ni si enikan se jinle to. Ni igba miran, ninu okan re yi kanna, o tun le ni ikorira, ibinu, tabi owu. Olorun nfe ki a feran oun pelu gbogbo okan wa. Ni igba gbogbo ni o nse ayewo okan wa. Beni Esu paapa nfe wo inu okan re lati le ma se akoso re; ki o ba le ba aye re je.

**OHUN TI OLORUN PESE FUN O:**

Bi iwo ba gba wipe Olorun le gba o la, ti o si setan lati yipada kuro ninu ese re, ki o gba idariji nipase omo re tiise Jesu Kristi; Olorun yoo fi o se ore re, yoo si fun o ni ebun tiise iye ayeraye. Olorun yoo ma gbe inu aya re nipase Emi Re. Yoo dabobo o ninu aburu gbogbo, yoo si bukun o bi o ti n gbekele le e.




**OHUN TI SATANI PESE FUN O:**

Anfani gbigbe inu ese bayi, sugbon lopin re… ki o le ma gbe pelu re (Satani) titi layelaye ni orun apadi. Ojo kan mbo ti Olorun yoo ju Satani ati gbogbo awon ti won nse tire sinu ina orun apadi

Ninu ina orun apadi, Satani ati awon ti won nse tire yoo ma je iya kikoro titi layelaye; sibesibe won koni ku. Kise awon ohun buburu ti won se ni ile aye ni yoo gbe won de orun apadi na bikose nitori wipe won ko gba ipese Olorun fun idariji ese won; nipa bee, won ko gba ki Olorun je ore ati olugbala won.

Je ki n bere ibeere pataki yi lowo re.

## TANI O NSAKOSO OKAN RE LOWOLOWO BAYI? SE OLORUN NI TABI SATANI?

Oseeese ki aworan yi ki o ran o lowo lati mo otito. Se akiyesi okan okunrin yi daada. Satani wa ni aarin gbungbun okan re, beeni kise oun nikan ni o wa mbe. Awon eranko ti won wa pelu re yi nse apere awon ohun buburu miran ti won wa ninu okan okunrin na. Awon nkan buburu wonyi ni a npe ni ese. Ewo ninu awon ese wonyi ni iwo mo? Eye Ogongo ninu aworan yi je apere wipe Igberaga wa ninu okan re. Awon ese miran wa nibe pelu, bii ifekufe ati iwa aimo (Ewure), ilepa iwa egbin(Elede), emi aje (Ijapa), ikorira ati ibinu (Ekun), owu jije (Ejo), ati ojukokoro (Opolo). Eriokan okunrin yi (irawo) ti sokunkun.



Oju yi n se afihan nipa Olorun ti o n wo okan eniyan (1 Samuel 16:7). Olorun mo ohun ikoko okan gbogbo eniyan. Lowolowo bayi, Olorun nri ohun gbogbo ti o wa ninu okan re… kosi ohun ti o le fipamo fun u.



## OLORUN FERAN RE!

Olorun fe gba o la kuro ninu ese re ati kuro ninu igbekun Satani. Sugbon ki o le seese fun Olorun lati gba iwo la, enikan lo ti san gbese ese re -- eni naa ti fi ara re rubo, o si ti je iya ti o to si iwo lati je. Nigbana ni o to seese fun Olorun lati dariji o. Eni naa ni Jesu Kristi, Omo Olorun. Omo Olorun ni Jesu lati atetekose, beenani o je bayi; yoo si maaje bee ni igba gbogbo.

Oun je mimo, eni rere ni, o si je eni pipe, sugbon o moomo fi orun sile wa si ile aye yi ki o le fi ara re rubo fun ese. Oku iku ti o ye ki iwo ku, ki iwo ba le ri idariji gba, ki osi di ore pelu baba Re.

*Nje O ri Aworan na?*

Ohun ti Jesu se fun o niyi. Oku nipa kikan ti won kan owo ati ese re mo Igi Agbelebu. O si ti ipase bee di eni egun nitori ki egun le pare kuro lori iwo titi layelaye. Eje san jade lara re nigbati o ku. Eje na si ni agbara lati we okan re mo tonitoni, ki o si tun dabobo o lowo gbogbo ewu. Ife nla ni Olorun ni fun o. O mura tan lati le Esu ati ese jade kuro ninu okan re ati ninu aye re. Olorun nfe ki iwo yipada si oun, ki o si gbekele oun fun igbala re.

## JE OLOOTO SI ARA RE!

Je olooto, ki o si gba wipe elese ni iwo, ati wipe o ni lati gba ife ati idariji ese ti Olorun ti pese fun o. Nibayi, gbadura si Olorun wipe ki o dariji o. Oun setan lati dariji o nitori wipe O ti fi Jesu rubo fun gbogbo ese ti iwo ti se.

*"Oluwa Olorun, mo ti dese. Bi mo ti ri aworan yi ni mo ri wipe ese wa ninu aye mi. Satani ni o nse akoso aye mi, o si fe pami run. Jowo dari ese mi ji mi, ki o si le Satani ati ese jade kuro ninu okan mi ati kuro ninu aye mi bayi. Ran omo re, Jesu Kristi, ati Emi Mimo re si inu okan mi lati gba mi; ki o si pa mi mo kuro ninu ewu gbogbo. Iwo Olorun ni o le se eyi nitori agbara re ju ti Satani lo. Iwo nikansoso ni Olorun otito. Olorun to tobi julo, ti o lagbara julo ni o. mo fe ki o je Olorun mi lati oni yi lo."*



Bibeli, iwe mimo Olorun wipe bi iwo ba jewo ese re tooto gegebi o ti se yi, olooto ni Olorun, yoo dari ji o, yoo si we okan re mo tonitoni. Bakanna, Oun yoo gba o; yoo si tun dabobo o kuro lowo agbara Satani ati orun apadi. Aworan yi nse afihan ohun ti o nsele lowolowo bayi. Imole Olorun n tan yika, Satani ati ese si n sa jade! Emi Olorun. bi eye Adaba ninu aworan yi, n tan imole sinu okan re lowolowo bayi, nitoripe imole ni Olorun.

# IPAARO NLA

Wo aworan yi — Emi Mimo wa mbe. Gbadura wipe ki Olorun fi Emi Alafia re kun inu okan re, ki O si da ibukun re sori re! Olorun fi oore ati ododo Jesu, omo re fun o, ropo awon ese re.



Ododo tumo si wipe iwo wa ninu ajosepo ti koni abawon pelu Olorun (o tumo si wipe o ti ni emi rere ti Jesu ninu okan re), ati wipe oju alailese ni Olorun fi nwo o bayi ninu Jesu. Nibayi, iwo ti ni anfani lati de ibi mimo re.




Iwo yoo di ore Olorun nigbati O ba ti dari ese re ji o; ti o si gba ebun ododo Olorun. Nigbati o ba ti gba wipe nitori tire ni Jesu se ku, nigbana ni iwo yoo ri idariji gba, ti iwo yoo si di eniyan titun.

Jowo ko akosile si alafo ti o wa nisale yii, ki o je akosile nipa ara re; ki o si fi akosile na ranse bi atejise ori ero alatagba. Logan ni ao kan si o lati fun o ni ounje emi ti yoo ran o lowo lati dagba kun oju osuwon.

Ti o ba ti gba Jesu Kristi gege bi Oluwa ati Olugbala re tabi o n fe alaye sii,Jowo te atejise si:

*ehcnigeria1@gmail.com*

Maa fe lati gba adura fun o ati lati ki o ku orire lori ominira re kuro ninu ahamo (ide) satani

Ti o ba fe iwe pelebe yii si jowo kan si
https://www.ehcnigeria.org/bible-courses/

**Every Home for Christ Nigeria**

7, Adekunle Akala St., Off Fatai Irawo St.,
Ajao Estate, By International Airport Road,
Lagos

+234 (1) 293 2331 | +234 (0) 815 5501 000
+234 - 815 550 2000

info@ehcnigeria.org | www.ehcnigeria.org